# ORI OKE INA ATI IṢẸ IYANU

*Olu Ile Iṣẹ Iranṣẹ, Ipinlẹ Eko, Nigeria.*

## ETO IPADE AGBARA GBỌDỌ PARỌ ỌWỌ AṢAYAN

### OGUN LODI SI AILERA (OṢU KEJE, ỌDUN 2020)

1. Orin Iyin
2. Ijẹwọ Bibeli: Orin Dafidi 91 ati 46
3. Orin mẹta nipa ẹjẹ Jesu.
4. Baba, a jẹwọ, a si ronupiwada kuro ninu awọn ẹṣẹ ti o ṣi ilẹkun silẹ fun ajakalẹ arun yi, ni orukọ Jesu.
5. A bẹbẹ fun aanu ati idariji, ni orukọ Jesu.
6. Oluwa, jẹ ki aanu Rẹ fọhun, ki O si dariji wa gẹgẹ bii orilẹ-ede, ni orukọ Jesu.
7. Oluwa, jẹ ki agbara iwosan Rẹ bẹrẹ si ni ṣiṣẹ lori ilẹ wa, ni orukọ Jesu.
8. A gbede, a si lee jade, dragoni alade lati ila-oorun, ni orukọ Jesu.
9. Ajẹsara atokewa, nipa ẹjẹ Jesu, ṣiji bo awọn oṣiṣẹ eto ilera wa, ni orukọ Jesu.
10. Agbara Ọga Ogo julọ, ṣiji bo awọn ti nwa iwosan ati abo, ni orukọ Jesu.
11. Oluwa, fun awọn adari wa ni ọgbọn atokewa lati k'apa iṣẹlẹ yi, ni orukọ Jesu.
12. Gbogbo ẹmi ika, ti wọn yan lati gba ẹmi mi, ṣegbe, ki o si yọ danu bii ori ninu ina, ni orukọ Jesu.
13. Àrá ina Ọlọrun, tuuka, paarun, ki o si fọ si wẹwẹ, gbogbo ipejọpọ lodi si iwalaaye mi, ni orukọ Jesu.
14. Odi ti ẹjẹ Jesu, yi emi ati idile mi ka, ipa buburu iyowu ti o ba sunmọ wa yoo jona, ni orukọ Jesu.
15. Oluwa, jẹ ki ibujoko agbara ti ajakalẹ arun yi ninu awọn ọrun ati ninu omi fọ si wẹwẹ, ni orukọ Jesu.
16. Iwọ afẹfẹ nla lati aginju, dide, ṣawari orisun ajakalẹ arun yi, ni orukọ Jesu.
17. Ẹjẹ Jesu, ṣijibo gbogbo eniyan ti mbẹ ni orilẹ-ede yi, ki o si dabobo wọn kuro lọwọ iku, ni orukọ Jesu.
18. Bi mo ti ngbe ninu apo ina atokewa,mo di ko ṣee gbamu fun agbara ailera iyowu, ni orukọ Jesu.
19. Iwọ afẹfẹ Ọlọrun, dide, ki O si gba irunu oro kuro ni ilẹ wa, ni orukọ Jesu.
20. Nipa agbara ti mbẹ ninu ẹjẹ Jesu, a mọ pẹpẹ iṣẹgun, iyin, ijọsin si Jehofah s'oke lori ilẹ ati ni awọn orilẹ-ede wa, ni orukọ Jesu.
21. A paṣe ki afẹfẹ pọ gbogbo irugbin ati ohun elo iku ti o ti fi pamọ, ni orukọ Jesu.
22. Ẹjẹ irekọja ti Jesu, ṣijibo orilẹ-ede wa, ni orukọ Jesu.
23. Ẹjẹ irekọja ti Jesu, ṣijibo ilẹ wa, ni orukọ Jesu.
24. Ẹjẹ irekọja ti Jesu, ṣijibo emi ati idile mi, ni orukọ Jesu.
25. Nipa agbara ti mbẹ ninu ẹjẹ Jesu, a dẹkun itankalẹ ajakalẹ arun yi, ni orukọ Jesu.
26. Nipa àrá agbara Rẹ, Oluwa, gbá agbara ajakalẹ arun yi danu, ni orukọ Jesu.
27. Iwọ ajakalẹ arun, gbọ ọrọ Oluwa, o ti to gẹẹ, ku, ni orukọ Jesu.
28. Gbogbo irunu awọn jẹranjẹran ati mujẹmujẹ, a da ọ duro ki o to da wa duro, ni orukọ Jesu.